lati mu ẹ̀bùn yin gòkè lọ si Jerusalẹmu. (2 Kor 8:18.)

4. Bi o ba si yẹ ki emi lọ pẹ̀lú, wọn o si bá mi lọ.

**Ètò ìrìn àjò ti Paulu.**

5. Ṣugbọn emi o tọ̀ yin wá, nigba ti emi bá ti kọjá lọ laarin Makedonia: nitori emi o kọjá laarin Makedonia. (A.A. 19:21.)

6. Boya emi o si duro pẹlu yín, tabi ki ntilẹ̀ lo akókò òtútù, ki ẹyin le sìn mí ni ọ̀nà àjò mi, níbikíbi ti mo ba nlọ. (A.A. 15:3.)

7. Nitori emi kò fẹ kàn ri yín bayìí nigba ìkọjá lọ mi; nitori emi nreti àti dúró lọ́dọ̀ yin diẹ, bi Oluwa bá fẹ́. (A.A. 18:21.)

8. Ṣùgbọ́n emi o duro ni Efesu títí di Pentikosti.

9. Nitori pe ilẹ̀kùn nla lati ṣe iṣẹ́ gidi ṣi sílẹ̀ fun mi, ọ̀pọ̀lọpọ̀ si ni àwọn ọ̀tá ti nbẹ.

10. Njẹ bi Timoteu bá dé, ẹ jẹ́ ki o wà lọdọ yin laibẹ̀rù: nitori oun nṣe iṣẹ Oluwa, bi emi pẹlu ti nṣe. (A.A. 16:1; 19:22; 1 Kor 15:58.)

11. Nitori naa ki ẹnikẹni má ṣe kẹgan rẹ̀. Ṣugbọn ẹ sin in jade lọna-àjò ni alaafia, ki oun lè tọ̀ mí wá; nitori ti emi nwọ ọna rẹ̀ pẹlu awọn arakunrin. (1 Tim 4:12; A.A. 15:33.)

12. Ṣugbọn ni ti Apollo arakunrin wa, mo bẹ ẹ pupọ lati tọ̀ yín wa pẹlu awọn arakunrin: Ṣugbọn ki i ṣe ìfẹ́ rẹ̀ rárá lati wà nisinsinyìí; ṣugbọn oun o wá nigba ti o bá ní akoko ti o wọ̀. (A.A. 18:24; 1 Kor 1:12; 3:5,6.)

**Ọrọ àsọpari ati ìkíni, ati oore-ọfẹ.**

13. Ẹ maa ṣọra, ẹ duro gangan ni igbagbọ, ẹ ṣe bi ọkunrin, ẹ jẹ alagbara (Filp 1:27; 2 Tess 2:15; Ef 6:10.)

14. Ẹ maa fi ìfẹ́ ṣe gbogbo nkan yin. (1 Kor 14:1.)

15. Njẹ mo bẹ yin, ará ẹ sá mọ ilé Stefana, pe awọn ni àkọ́so Akaia, ati pe, wọn sì ti fi ara wọn fun iṣẹ-ìranṣẹ awọn eniyan mímọ́. (Rom 16:5; 2 Kor 8:4; Heb 6:10.)

16. Ki ẹyin tẹriba fun iru awọn bawọnyìí, ati fun olukuluku olùbáṣiṣẹ́ pọ pẹlu wa ti o si nṣe làálàá. (Heb 13:1.)

17. Mo yọ̀ fun wiwa Stefana ati Fortunatu ati Akaiku: nitori eyi ti o kù nipa ti yin wọn ti fi kun un. (2 Kor 7:6, 11: 9.)

18. Nitori ti wọn tu ẹ̀mí mi lara ati tiyin: nitori naa ẹ maa gba iru awọn ti o ri bẹẹ. (2 Kor 7:13; Filp 2:29.)

19. Awọn ijọ ni Asia ki yin, Akuila ati Prikilla ki yin pupọ ninu Oluwa, pẹlu ijọ ti o wà ni ile wọn. (A.A. 16:6; Rom 16:5.)

20. Gbogbo awọn arakunrin ki yin, Ẹ fi ìfẹnukonu mímọ́ ki ara yin.

21. Ìkíni ti emi Paulu, lati ọwọ emi tikarami wá.

22. Bi ẹnikẹni kò bá ní ìfẹ́ Jesu Kristi Oluwa, jẹ ki o di *Anatema. Maranata! (Ef 6:24; Rom 9:3.)

23. Oore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa ki o wà pẹlu yin! (Rom 16:20.)

24. Ifẹ mi wa pẹlu gbogbo yin ninu Kristi Jesu. (Amin.)

(22) *"Anatema" tumọsi Ẹni-Ifibu, "Maran-ata" si tumọsi, Oluwa wa, Maabọ̀.

47

# AWỌN ARA KỌRINTI KEJI

**(A.D. 60)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni.**

PAULU Aposteli Jesu Kristi nipa ìfẹ́ Ọlọrun, ati Timoteu arakunrin wa, si ijọ Ọlọrun ti o wà ní Kọrinti, pẹ̀lú, gbogbo awọn eniyan-mímọ́ tí o wà ní gbogbo Akaia: (Kol 1:1;1Tim 1:1; 1 Kor 1:1.)

2. Oore-ọ̀fẹ́ si yín ati alaafia lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun Baba wá, ati Jesu Kristi Oluwa. (Rom 1:7; 1 Kor 1:3; Gal 1:3.)

**Paulu ndúpẹ́ o si nyin Ọlọrun logo.**

3. Olubukun ni Ọlọrun, ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, Baba ìyọ́nú, ati Ọlọrun ìtùnú gbogbo; (Ef 1:3; 1 Pet 1:3; Rom 15:5.)

4. Ẹni ti ntù wa ninu ni gbogbo wàhálà wa, ki awa lè maa tu awọn tí ó wa ninu wàhálà kí wàhálà ninu, nipa ìtùnú naa ti a fi ntu awa tikarawa nínú lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá. (2 Kor 7:6,7,13.)

5. Nitori pe bi ìyà Kristi ti di pupọ ninu wa, gẹgẹ bẹ̃ ni ìtùnú wa di pupọ pẹ̀lú nipa Kristi. (2 Kor 4:10; Kol 1:24.)

6. Ṣugbọn bi a ba si npọ́n wa loju, o jẹ fun ìtùnú ati ìgbàlà yín; tabi bi a ba ntù wá nínú, o jẹ fún ìtùnú ati ìgbàlà yín ti nṣiṣẹ́ lati mu yin ní irú ìfaradà ìyà kannaa ti àwá pẹlu njẹ. (2 Kor 4:15.)

7. Ati ireti wa nipa tiyín duro ṣinṣin, awa si mọ̀ pe, bí ẹyin ti jẹ alabapin ninu ìyà, bẹ̃ ni ẹyin yoo pin ninu ìtùnú naa pẹ̀lú. (Rom 8:17; 1 Tim 2:12.)

8. Ará, awa kò saa fẹ ki ẹyin wà ni àìmọ̀ nipa wàhálà wa, ti o dé bá wa ni Aṣia, niti pe a pọ́n wa loju gidigidi rekọja agbara wa, tobẹ̃ ti ìrètí kò tilẹ̀ si fun ẹ̀mí wa mọ́: (A.A. 19:23.)

9. Nitootọ́, a tilẹ̀ ti ro o ninu ara wa pé a ti gba idalẹbi ikú. Ṣugbọn èyí ni lati má mu wa gbẹkẹle ara wa bikoṣe Ọlọrun ti nji òkú dìde: (Jer 17:5,7.)

10. Ẹni tí o gbà wá kuro ninu irú titobi ikú bẹ̃, yoo si tun gbà wá; oun ni awa gbẹkẹ wa lé pe yoo si maa gbà wa sibẹsibẹ; (2 Pet 2:9.)

11. Ẹyin pẹlu gbọdọ maa fi àdúrà yin ṣe iranlọwọ fun wa, ki o baa lè jẹ pe ọpọlọpọ yoo le maa bá wa dupẹ fun ibukun ti a ri gbà ni idahun si adura pupọ. (Rom 15:30; Filp 1:19; 2 Kor 4:15.)

**Paulu yí ipinnu rẹ̀ padà.**

12. Nitori èyí ni ìṣògo wa, ẹ̀rí lati inú ẹ̀rí-ọkàn wa, pe, pẹlu ìwà-mímọ́ ati ododo Ọlọrun, ki i ṣe nipa ọgbọ́n ti ara, bikoṣe nipa oore-ọfẹ Ọlọrun ni awa nhùwà ni ayé, ati paapaa si yin lọpọlọpọ. (2 Kor 2:17; 1 Kor 2:4,13.)

13. Nitori pe àwa kò kọ̀wé ohun miran sí yin ju èyí ti ẹyin le kà lọ, tabi ti ẹyin le mòye rẹ̀ pẹlu: mo si nírètí pe ẹyin o lẹ moye rẹ̀ sii títí de òpin:

14. Gẹgẹ bí ẹyin sì ti jẹ́wọ́ wa pẹlu ni apakan pé, àwa ni iṣogo yín, gẹgẹ bi ẹyin pẹlu ti jẹ iṣogo wa ni ọjọ Jesu Oluwa. (Rom 6:17; Ef 5:2; Filp 4:18; 1 Kor 12:8.)

15. Ati ninu igbẹkẹlẹ yìí ni mo ti ngbèrò lati tọ̀ yin wá niṣaaju, ki ẹyin le ni ayọ̀ nígbàkejì; (1 Kor 4:19; Rom 1:11; 15:29.)

16. Ati lati kọja lati ọdọ yin lọ si Makedonia, ati lati tún wá sọdọ yín lati Makedonia, ati lati mu mi lati ọdọ yin lọ si Judea. (1 Kor 16:5–7.)

17. Nitori naa nigba ti emi ngbèrò bẹ̃, emi ha ṣiyemeji bí? Tabi awọn ohun ti mo pinnu, mo ha pinnu wọn gẹ́gẹ́ bi ti ara bí, pe ki o jẹ "bẹẹni, bẹẹni", ati "bẹẹkọ́, bẹẹkọ́" lọ́dọ̀ mi? (2 Kor 10:2,3.)

18. Ṣugbọn bi Ọlọrun ti jẹ́ olootọ́, ọ̀rọ̀ wa fun yin ki i ṣe bẹẹni ati bẹẹkọ́. (1 Kor 1:9; 2 Kor 2:17.)

19. Nitori pé Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun, ẹni ti a ti waasu rẹ̀ laarin yín nipasẹ wa, àní nipasẹ emi ati Silfanu ati Timoteu, ki i ṣe bẹẹni ati bẹẹkọ́, ṣugbọn ninu rẹ̀ ni bẹẹni. (Matt 16:16; 1 Tess 1:1; Heb 13:8.)

20. Nitori ti gbogbo ileri Ọlọrun di bẹẹni ninu rẹ̀. Nitori idi èyí ni a ṣe nwi pé "Àmín," nipasẹ̀ rẹ̀ si ogo Ọlọrun. (Rom 15:8,9; 1 Kor 14:16.)

21. Njẹ nisinsinyìí, ẹni ti o fi ẹsẹ̀ wa múlẹ̀ pẹlu yín ninu Kristi, ti o si fi àmì òróró yàn wá, ni Ọlọrun; (1 Kor 1:8; 1 Jhn 2:20,27.)

22. Ẹni ti o si ti fi edídí di wa pẹlu, ti o si ti fi Ẹmi rẹ̀ si wa ni ọkàn gẹgẹ bi ẹri-idaniloju (Ef 1:13.)

**Idi ti o fi yi ipinnu rẹ̀ padà.**

23. Mo si pe Ọlọrun ṣe ẹlẹri ọkan mi

pé, nitori lati da yín si ni emi ko ṣe ti wá si Korinti. (Gal 1:20; 1 Kor 4:21; 2 Kor 2:3.)

24. Ki i ṣe nitori ti àwa jẹ gàba lori igbagbọ yín; ṣugbọn awa jẹ́ oluranlọwọ ayọ̀ yin: nitori ẹyin duro nipa ìgbàgbọ́. (1 Pet 5:3; Rom 11:20; 1 Kor 15:1.)

## ORI 2.

SUGBỌN mo ti pinnu èyí ninu emi tikarami pe, emi ki yoo tun fi ibanujẹ tọ̀ yin wá. (2 Kor 1:23.)

2. Nitori pé bi emi bá mu inu yin bàjẹ́, njẹ tani ẹni ti ìbá mu inu mi dùn, bikoṣe ẹni ti mo ti bà ninu jẹ́? (2 Kor 7:8.)

3. Emi sì kọ̀wé bi mo ti kọ si yin pé, nigba ti mo bá si de, ki emi máṣe ni ibanujẹ́ lọdọ awọn ti ìbá mu mi ní ayọ: nitori ti mo ni igbẹkẹlé ninu gbogbo yin, nitori ayọ̀ mi yoo jé ayọ̀ fun gbogbo yín. (2 Kor 12:21; 7:16; 8:22.)

4. Nitori pe ninu ọpọlọpọ wàhálà ati irora ọkàn mi ni mo ti fi ọpọlọpọ omijé kọwe si yin; ki i ṣe nitori ki a le bà yin ninu jẹ́, ṣugbọn ki ẹyin baa le mọ ìfẹ́ ti mo ni si yin lọpọlọpọ rékọjá. (2 Kor 7:8,9,12.)

**Didaríjì ẹlẹ́ṣẹ̀ ti o ronupiwada.**

5. Ṣugbọn bi ẹnikẹni ba fa ohun ibanujẹ, kii ṣe emi ni o bà nínú jẹ́, bikoṣe ẹyin tìkárayin, níwọ̀n ìyówù ki o jẹ́; un kò fẹ́ sọ ọ́ lọna lile jù (1 Kor 5:1,2.)

6. Ìyà naa tí ọpọlọpọ ti fi jẹ irú eniyan bẹẹ, o to fun un. (1 Kor 5:4,5.)

7. Kàkà bẹẹ, ẹyin iba kuku dáríjì í, ki ẹ si tù u nínú lọ́nàkọnà, ki ọpọlọpọ ibanujẹ má ba a bo irú eniyan bẹ ẹ mọ́lẹ̀. (Gal 6:1; Ef 4:32.)

8. Nitori naa mo bẹ yin, ẹ fi ifẹ yin hàn dájú si oluwarẹ̀.

9. Nitori eyi naa pẹlu ni mo ṣe kọwe, ki emi baa lè ri ẹ̀rí dìmú nipa yín, bi ẹyin bá jẹ́ olùgbọ́ràn ọmọ ni ohun gbogbo. (Filp 2:22; 2 Kor 7:15;10:6.)

10. Ṣugbọn ẹni ti ẹyin ba fi ohunkohun jì fun, emi fi jì pẹlu: nitori ohun ti emi pẹlu ba ti fi jì, bi mo ba ti fi ohunkohun jì, nitori tiyín ni mo ṣe fi jì niwaju Kristi.

11. Ki Satani ma baa rẹ́ wa jẹ: nitori awa ko ṣe alaimọ̀ arekereke rẹ̀. (Matt 4:10; Luk 22:31; 2 Kor 4:4; 1 Pet 5:8.)

**Yiyọ ayọ̀ iṣẹgun ninu Iṣẹ-iranṣẹ.**

12. Ṣugbọn nigba ti mo de Troa lati waasu ihinrere Kristi, ti ilẹkun si ṣí silẹ fun mi lati ọ̀dọ̀ Oluwa wá, (A.A. 16:8; 1 Kor 16:9.)

13. Emi kò ni alaafia lọkan mi, nitori ti emi ko ri Titu arakunrin mi: ṣugbọn nigba ti mo ti dágbére fun wọn, mo rekọja lọ si Makedonia, (2 Kor 7:5,6; Mk 6:46; Rom 15:26.)

14. Ṣugbọn ọpẹ́ ni fún Ọlọrun, ẹni ti nyọ ayọ̀ iṣẹgun lori wa nigbagbogbo ninu Kristi, ti a sì fi oórùn ìmọ̀ rẹ̀ han nipa wa nibigbogbo. (Rom 6:17; Ef 5:2; Filp 4:18; 1 Kor 12:8.)

15. Nitori òórùn didun Kristi ni awa jẹ́ fún Ọlọrun, ninu awọn ti a ngbàlà, ati ninu awọn ti o nṣègbé: (Ef 5:2; Filp 4:18; 2 Kor 4:3.)

16. Fun awọn kan, awa jẹ ọ̀órùn ikú si ikú, ati fún awọn miran òórùn ìyè si ìyè. Tani o ha si tọ́ fun nkan wọnyìí? (Jhn 9:39; 1 Pet 2:7.)

17. Nitori awa kò dabi awọn ọpọlọpọ, ti nfi ọ̀rọ̀ Ọlọrun ṣòwò-jẹun; ṣugbọn bi nipa òtítọ́ inu, ṣugbọn bi ẹni ti a rán lati ọdọ Ọlọrun wá, niwaju Ọlọrun ni awa nsọ̀rọ̀ ninu Kristi. (2 Kor 4:2; 1:12; 12:19.)

## ORI 3.

**Iṣẹ-Iranṣẹ ti a fi le ni lọ́wọ́.**

AWA ha tún bẹ̀rẹ̀ lati maa yin ara wa bí? Tabi awa ha nfẹ́ iwe ìyìn sọdọ yín, tabi lati ọdọ yin gẹgẹ bi ẹlomiran ti nṣe? (2 Kor 5:12; 12:11; A.A. 18:27.)

2. Ẹyin funrayin ni iwe ìyìn wa, ti a ti kọ si yin ni ọkàn, ti gbogbo eniyan sì mọ̀, ti wọn si nkà. (1 Kor 9:2.)

3. Ẹyin si nfi hàn pe, iwe ti a gbà silẹ̀ lati ọ̀dọ̀ Kristi ni yin, ki i ṣe èyí ti a fi tàdáwà kọ, bikoṣe Ẹmí Ọlọrun alààyè; ki i ṣe ninu wàláà okuta bikoṣe ninu wàláà ọkàn ẹran. (Jer 31:33; Esk 11:19.)

**Iṣẹ Iranṣẹ ti o logo.**

4. Irú igbẹkẹle yìí ni awa ni nipasẹ̀ Kristi ṣọdọ Ọlọrun: (Ef 3:12.)

5. Ki i ṣe pé awa tó funrawá lati ṣiro ohunkohun bí ẹni pé lati ọ̀dọ̀ awa tìkarawa; ṣugbọn lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun ni tito wa; (2 Kor 2:16; 15:10; 1 Kor 5:4,5.)

6. Ẹni ti o mú wa tó bí iranṣẹ majẹmu titun; ki i ṣe ní ti ìwé-àkọọ́lẹ̀, bikoṣe ti ẹ̀mí: nitori ìwé-àkọọ́lẹ̀ a maa pani, ṣugbọn ẹmi a maa sọni di ààyè. (Heb 8:6,8; Gal 3:10; Jhn 6:63.)

7. Ṣugbọn bi iṣẹ-iranṣẹ ti ikú, ti a ti kọ ti a si ti gbẹ́ si ara okuta, bá jẹ́ ologo, tobẹẹ ti awọn ọmọ Israeli kò le tẹjúmọ́ wíwo ojú Mose nitori ogo ojú rẹ̀ (ogo ti nkọjá lọ); (Eks 34:29–35.)

8. Yoo ha ti rí ti iṣẹ́-iranṣẹ ti ẹmi ki yoo kúkú jẹ́ ogo jù?

9. Nitori pé bi iṣẹ-iranṣẹ ìdálẹ́bi bá jẹ ologo, melomelo ni iṣẹ-iranṣẹ òdodo yoo tayọ jù ú ni ogo. (ẹsẹ 7; Rom 1:17; 3:21.)

10. Nitori, èyí ti a ti ṣe logo rí, ko logo mọ bayìí, nitori ogo ti o tayọ.

11. Nitori pé bi èyí ti nkọja lọ bá logo, melomelo ni èyí ti o dúró ki yoo ni ogo.

12. Njẹ nitori naa bi a ti ni irú ireti bi èyí, awa nfi ìgbóyà pupọ sọ̀rọ̀. (2 Kor 7:4; Ef 6:19.)

13. Ki i si ṣe bi Mose, ẹni ti o fi ìbojú bo ojú rẹ̀, ki awọn ọmọ Israeli ma baa le tẹjumọ wíwo òpin èyí ti nkọja lọ. (ẹsẹ 7; Eks 34:33.)

14. Ṣugbọn ojú-inu wọn fọ́: nitori pé títí di oni oloni nipa kíka majẹmu laelae, iboju kannaa ṣì wà laiká sokè; nitori pé ninu Kristi ni a ti lè mú iboju naa kúrò. (Rom 11:7; A.A. 13:15; ẹsẹ 6.)

15. Ṣugbọn titi di oni oloni, nigbakugba ti a bá nka Mose, iboju naa nbẹ lọ́kàn wọn.

16. Ṣugbọn nigba ti oun bá yipada si Oluwa, a o mu iboju naa kúrò. (Rom 11:23.)

17. Njẹ Oluwa ni Ẹmí naa: nibi ti Ẹmí Oluwa bá sì wà, nibẹ ni ominira gbé wà. (1 Kor 15:45; Isa 61:1,2; Jhn 8:32.)

18. Ṣugbọn gbogbo wa nwo ogo Oluwa laisi iboju bi ẹni pé ninu àwòjíji, a si npawádà sí àwòrán kannaa lati ogo dé ogo, àní bí lati ọ̀dọ̀ Oluwa ti i ṣe Ẹmí. (1 Kor 13:12; 2 Kor 4:4,6; Rom 8:29.)

## ORI 4.

**Iṣẹ-iranṣẹ ti otitọ.**

NITORI naa bi awa ti ni iṣẹ́-iranṣẹ yìí, gẹ́gẹ́ bi a ti ri aanu gbà, ààrẹ̀ ko mú wa; (2 Kor 3:6; 1 Kor 7:25.)

2. Ṣugbọn awa ti kọ gbogbo ohun ìkọ̀kọ̀ ti o ni ìtìjú sílẹ̀, awa kò rìn ni ẹ̀tàn, bẹẹ ni awa kò fi ọwọ́ ẹ̀tàn mú ọ̀rọ̀ Ọlọrun; ṣugbọn nipa fífi otitọ hàn, awa nfi ara wa le ẹ̀rí-ọkàn olukuluku eniyan lọ́wọ́ niwaju Ọlọrun. (2 Kor 2:17.)

3. Ṣugbọn bayìí, bi ihinrere wa ba sì farasin, o farasin fun awọn ti o nṣègbé. (2 Kor 2:12; 3:14; 1 Kor 1:18.)

4. Ninu awọn ẹni ti ọlọrun ayé yìí ti sọ ọkàn awọn alaigbàgbọ́ di afọ́jú, ki imọlẹ ihinrere Kristi ti o lógo, ẹni ti i ṣe aworan Ọlọrun, máṣe mọ́lẹ̀ ninu wọn. (Jhn 12:31; Kol 1:15; Jhn 1:18.)

5. Nitori awa kò waasu àwa tikarawa, bikoṣe Kristi Jesu Oluwa; àwa tikarawa sì jẹ́ ẹrú yin nitori Jesu. (1 Kor 1:13,23; 9:19.)

6. Nitori Ọlọrun ni ẹni ti o wi pé, "Ki imọlẹ o mọ́lẹ̀ lati òkùnkùn jade!" oun ni o ti nmọ́lẹ̀ lọkan wa, lati fun wa ni imọlẹ ìmọ̀ ogo Ọlọrun ni ojú Jesu Kristi. (Gen 1:3; 2 Pet 1:19.)

**Iṣẹ-Iranṣẹ ti o mu Inunibini atí Ipọnju lọ́wọ́.**

7. Ṣugbọn àwa ni iṣura yìí ninu ohun-èlò amọ̀, ki ọlá nlá agbara naa lè

jẹ ti Ọlọrun, ki o má ṣe ti ọdọ̀ wa wá. (2 Kor 5:1; 1 Kor 2:5.)

8. A npọ́n wa lójú niha gbogbo, ṣugbọn ara kò ni wá: a ndaamu wa, ṣugbọn a ko sọ ìrètí nù. (2 Kor 7:5; 6:12.)

9. A nṣe inunibini si wa, ṣugbọn a kò kọ̀ wá silẹ; a nrẹ̀ wa silẹ̀ ṣugbọn a kò sì pa wá run; (Jhn 15:20; Heb 13:5; Psm 37:24.)

10. Nigbagbogbo awa nru ikú Jesu Oluwa kiri ni ara wa , ki a lè fi ìyè Jesu hàn pẹ̀lú lara wa. (Gal 6:17; Rom 8:17.)

11. Nitori pé nigbagbogbo ni a nfi awa ti o wà laaye fun ikú nitori Jesu, ki a le fi ìyè hàn ninu ara kíkú wa pẹlu. (Rom 8:36:)

12. Bẹẹ ni ikú nṣiṣẹ ninu wa, ṣugbọn ìyè ninu yín. (2 Kor 13:9.)

13. Awa ní ẹ̀mí igbagbọ kannaa, gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, emi gbagbọ, nitori naa ni emi ṣe sọ: awa pẹlu gbagbọ, nitori naa ni awa sì ṣe nsọ: (Psm 116:10.)

14. Awa mọ̀ pé, ẹni ti o ji Jesu Oluwa dide yoo sì jí wa dide pẹlu nipa Jesu, yoo si mu wa wà niwaju rẹ̀ pẹlu yin. (1 Tess 4:14.)

15. Nitori tiyín ni gbogbo rẹ̀, ki ọpẹ lè di pupọ fun ògo Ọlọrun gẹgẹ bi oore-ọfẹ ti ngbòrò si i sí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ awọn eniyan.

16. Nitori èyí ni ààrẹ̀ ko ṣe mu wa; ṣugbọn bi ọkunrin ti òde wa bá nparun, sibẹ ọkunrin ti inu wa ndi titun lojoojumo. (Rom 7:22; Kol 3:10.)

17. Nitori ipọnju diẹ kíun yìí npèsè ogo ti o ni ìwọ̀n ayeraye ti o pọ̀ rekọja silẹ fun wa. (Rom 8:18; 1 Pet 1:6.)

18. Niwọn bi a kò ti wo ohun ti a nrí, bikoṣe ohun ti a kò rí: nitori ohun ti a nri ni ti ìgbà isinsinyìí; ṣugbọn ohun ti a kò rí ni ti ayérayé. (Rom 8:24; Heb 11:1.)

ORI 5.

**Iṣẹ Iranṣẹ ti o nfẹ ìgboyà.**

NITORI awa mọ̀ pé, bi ilé àgọ́ wa ti ayé ba wó, awa ni ile kan lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun, ile ti a kò fi ọwọ́ kọ́, ti ayérayé ninu awọn ọrun. (2 Pet 1:13,14.)

2. Nitori nitootọ́ awa nkerora ninu èyí, awa si nfẹ gidigidi lati fi ilé wa ti ọrun wọ̀ wá: (Rom 8:23; ẹsẹ 4.)

3. Bi o ba ṣe pé a ti fi wọ̀ wá, a ki yoo bá wa ni ìhòhò.

4. Nitori awa ti nbẹ ninu àgọ́ yìí nkerora nitootọ́, kii ṣe nitori ti àwa yoo jẹ́ alaiwọṣọ, ṣugbọn pe a o wọ̀ wá ni aṣọ sii, ki ìyè baa lè gbe ara-kíkú mì. (1 Kor 15:53,54.)

5. Njẹ ẹni ti o ti pèsè wa fun nkan yìí ni Ọlọrun, ẹni ti o sì ti fi Ẹ̀mí fun wa pẹlu ni ẹ̀rí-idaniloju. (Rom 8:23; 2 Kor 1:22.)

6. Nitori naa awa ni ìgboyà nigbagbogbo, awa si mọ̀ pé, nigba ti awa nbẹ ni ilé ninu ara, awa kò si lọdọ Oluwa. (Heb 11:13,14.)

7. (Nitori pé nipa ìgbàgbọ́ ni awa nrìn, kii ṣe nipa rírí:) (1 Kor 13:12.)

8. Mo ni, awa ni ìgboyà, awa si nfẹ ki a kúkú ti inú ara kúrò, ki a sì lè wà ni ilé lọdọ Oluwa. (Filp 1:23.)

9. Nitori naa awa ndù ú, pe, bi awa bá wà ni ilé tabi bi a kò si, ki awa lè jẹ́ ẹni itẹwọgba lọdọ rẹ̀.

10. Nitori pé gbogbo wa ni yoo fi ara hàn niwaju itẹ́ idajọ Kristi; ki olukuluku lè gbà eyi ti o ṣe gẹgẹ bí èyí ti o ti ṣe ninu ara, ibaa ṣe rere ibaa ṣe buburu. (Rom 14:10; Ef 6:8.)

**Iṣẹ-Iranṣẹ ìlàjà ti a yàsọ́tọ̀.**

11. Nitori naa bi awa ti mọ ẹ̀rù Oluwa, awa nyi eniyan lọ́kàn padà; ṣugbọn a nfi wa hàn fun Ọlọrun; mo sì gbagbọ pé, a si ti fi wá hàn ni ọkàn yin pẹlu. (Heb 10:31; Jud 23; 2 Kor 4:2.)

12. Nitori awa kò sì ní maa tún yin ara wa si yin mọ́, ṣugbọn awa fi àyè fun yin lati maa ṣogo nitori wa, ki ẹ lè ni ohun ti ẹ o fi dá wọn lóhùn, awọn ti nṣogo lode ara ki i si ṣe ni ọkàn. (2 Kor 3:1; 1:14.)

13. Nitori naa bi orí wa ba bàjẹ́, fun Ọlọrun ni: tabi bi iyè wa ba wálẹ̀, fun yin ni. (2 Kor 11:1,16,17.)

14. Nitori ifẹ Kristi nrọ wá, nitori awa mọ bayìí pe, bi ẹnikan ba kú fun gbogbo eniyan, njẹ nigba naa gbogbo wọn ni o ti kú: (A.A. 18:5; Rom 5:15; Gal 2:20.)

15. O si ti kú fun gbogbo wọn, pe ki awọn ti o wà láàyè má si ṣe wà láàyè fun ara wọn mọ́, bikoṣe fun ẹni ti o kú nitori wọn, ti o si ti jinde. (Rom 14:7–9.)

16. Nitori naa lati isinsinyìí lọ awa kò mọ ẹnikan nipa ti ara mọ́; bi awa tilẹ ti mọ Kristi nipa ti ara, ṣugbọn nisinsinyìí awa kò mọ ọn bẹẹ mọ́. (2 Kor 11:18; Filp 3:4; Jhn 8:15.)

17. Nitori naa bi ẹnikẹni ba wa ninu Kristi, o di ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i, ohun titun ti de. (Rom 16:7; Gal 5:6; Ifh 21:4,5.)

18. Ohun gbogbo si ti ọdọ Ọlọrun wa, ẹni ti o si tipasẹ Jesu Kristi bá wa làjà sọdọ ara rẹ, ti o si ti fi iṣẹ́-iranṣẹ ìlàjà fun wa; (Rom 5:10.)

19. Èyí ni pé, Ọlọrun wà ninu Kristi, o nbá aráyé làjà sọdọ ara rẹ, kò si ka irekọja wọn si wọn lọrun; o si ti fi ọrọ ìlàjà lé wa lọwọ.

20. Nitori naa awa ni ikọ fun Kristi, bi ẹni pé Ọlọrun nti ọdọ wa ṣìpẹ̀ fun yin: awa nbẹ yin nipo Kristi, "Ẹ bá Ọlọrun làjà." (2 Kor 3:6.)

21. Nitori o ti fi ṣe ẹ̀ṣẹ̀ nitori wa, ẹni ti kò mọ ẹ̀ṣẹ̀kẹ́ṣẹ̀ rí: ki awa lè di òdodo Ọlọrun ninu rẹ̀. (1 Pet 2:22; 1 Jhn 3:5; Gal 3:13.)

ORI 6.

GẸGẸ bi alabaṣiṣẹpọ̀ pẹlu rẹ, njẹ, awa nbẹ yin ki ẹ máṣe gba oore-ọfẹ Ọlọrun lásán. (1 Kor 3:9; 2 Kor 5:20; Heb 12:15.)

2. Nitori o wi pe, "Emi ti gbohun rẹ ni àkókò itẹ́wọ́gbà, ati ni ọjọ́ igbala ni mo si ti ràn ọ́ lọ́wọ́." Kiyesi i, ni isinsinyìí ni àkókò itẹ́wọ́gbà; kiyesi i, ni isinsinyìí ni ọjọ igbala. (Isa 49:8.)

3. A ko si ṣe ohunkohun ni ohun ìkọ̀sẹ̀, ki iṣẹ́-iranṣẹ wa máṣe di ìsọ̀rọ̀ buburu sí. (Rom 14:13; 1 Kor 9:12; 10:32.)

4. Ṣugbọn ni ọna gbogbo awa nfi ara wa hàn bi awọn iranṣẹ Ọlọrun ninu ọpọlọpọ sùúrù, ninu ìpọ́njú, ninu àìní, ninu wàhálà.

5. Nipa, nínà, ninu túbú, nipa irukerudo, nipa iṣẹ, ninu ṣíṣọ́nà, ninu ìgbààwẹ̀. (2 Kor 11:23.)

6. Nipa iwa mimọ, nipa ìmọ̀, nipa ipamọra, nipa iṣeun, nipa Ẹmi Mimọ, nipa ifẹ àìṣẹ̀tàn,

7. Nipa ọ̀rọ̀ otitọ, nipa agbara Ọlọrun, nipa ihamọra ododo ni apá ọtun ati lápá osi. (2 Kor 4:2; 10:4; Ef 6:11,13.)

8. Nipa ọla ati ẹ̀gàn, nipa ihin buburu ati ihinrere: bi ẹlẹ̀tàn, ṣugbọn a jasi olootọ́;

9. Bi ẹni ti a ko mọ̀, ṣugbọn a mọ̀ wa dajudaju; bi ẹni ti nkú lọ, si kiyesi i, awa wà láàyè; bi ẹni ti a nà, a kò si pa wá; (Rom 8:36; 2 Kor 1:8–10; 4:10,11.)

10. Bi ẹni ti o kún fun ibanujẹ, ṣugbọn awa nyọ nigbagbogbo; bi tálákà, ṣugbọn awa nsọ ọpọlọpọ di ọlọ́rọ̀; bi ẹni ti kò ní nkan, ṣugbọn awa ni ohun gbogbo. (Rom 8:32; 1 Kor 3:21.)

**Ipe si Ìbákẹ́dùn.**

11. Ẹyin ara Korinti, a ti yà ẹnu wa si yin, ọkàn wa si ṣipayá. (Esk 33:22; 2 Kor 7:3; Isa 60:5.)

12. A kò ni yín lara nitori wa, ṣugbọn a nni yín lara nitori ifẹ ọkàn ẹyin tikarayin.

13. Ni sísanpadà lọ́nà kannaa (emi nsọ bi ẹni pe fun awọn ọmọdé), ẹ̀yin naa ẹ ṣípayá pẹlu. (1 Kor 4:14.)

**Ipe si iyasọtọ ninu ohun buburu gbogbo.**

14. Ẹ máṣe fi àìdọ́gba dàpọ̀ pẹlu awọn alaìgbàgbọ́: nitori idapọ kinni ododo ni pẹlu aiṣododo? Idapọ kinni imọlẹ si ni pẹlu okùnkùn? (Deut 7:2,3; 1 Kor 5:9,10; Ef 5:7,11; 1 Jhn 1:6.)

15. Ìrẹ́pọ̀ kinni Kristi ni pẹlu Beliali Tabi ìpín wo ni ẹni ti o gbagbọ ni pẹlu alaigbagbọ?

16. Ìrẹ́pọ̀ kinni tẹmpili Ọlọrun ni pẹlu òrìṣà? Nitori ẹyin ni tẹmpili Ọlọrun alààyè; gẹgẹ bi Ọlọrun ti wi pe, "Emi o gbe inu wọn, emi o sì maa rìn laarin wọn; emi o si jẹ Ọlọrun wọn, wọn o sì jẹ eniyan mi." (1 Kor 3:16; Jer 31:1; Esk 37:27; Lef 26:11,12.)

17. "Nitori naa ẹ jade kuro laarin wọn, ki ẹ sì ya ara yin si ọ̀tọ̀" ni Oluwa wi, "Ki ẹ máṣe fi ọwọ kan ohun àìmọ́; emi o si gbà yin, (Isa 52:11; Ifh 18:4.)

18. Emi o sì jẹ Baba fun yin, ẹyin o sì jẹ ọmọkunrin mi ati ọmọbinrin mi!", ni Oluwa Olọdumare wi. (Hos 1:10; Isa 43:6; 2 Sam 7:14.)

ORI 7.

NITORI naa, ẹyin olufẹ bi a ti ni ileri wọnyìí, ẹ jẹ́ ki a wẹ ara wa mọ́ kuro ninu gbogbo ẹ̀gbin ti ara ati ti ẹ̀mí, ki a sọ ìwà mímọ́ di pipe ninu ibẹru Ọlọrun. (2 Kor 6:17,18.)

**Bi bẹ̀bẹ̀ fun idajọ awọn ara.**

2. Ẹ gbà wá tọkàntọkàn; a ko fi ibi ṣe ẹnikẹni, a ko ba ẹnikẹni jẹ́, a ko ré ẹnikẹni jẹ. (2 Kor 6:12,13.)

3. Emi ko sọ èyí lati dá yin lẹbi; nitori mo ti wi ṣaaju pe, ẹyin wa ninu ọkàn wa ki a lè jùmọ̀ kú, ati ki a lè jumọ wà láàyè. (2 Kor 6:11,12.)

4. Mo ni ìgbóyà nla lati ba yin sọ̀rọ̀; iṣogo mi lori yin pọ; mo kun fun ìtùnú, mo si nyọ̀ rekọja ninu gbogbo iponju wa. (2 Kor 1:4,14; 3:12.)

**Paulu yọ̀ nigba ti o gbọ irohin rere si awọn ara Kọrinti.**

5. Nitori pe nigba ti awa tilẹ de Makedonia, ara wa kò balẹ̀, ṣugbọn a npọ́n wa lójú niha gbogbo, ìjà nbẹ lode, ẹ̀rù nbẹ ninu. (2 Kor 2:13; 4:8; Deut 32:25.)

6. Ṣugbọn ẹni ti ntu awọn onírẹ̀lẹ̀ ninu, ani Ọlọrun, o tù wa ninu nipa dide Titu; (2 Kor 1:3,4; ẹsẹ 13; 2 Kor 2:13.)

7. Ki i si ṣe nipa dide rẹ̀ nikan ṣugbọn nipa ìtùnú naa pẹlu ti ẹ ti tù ú ninu, nigba ti o rohìn fun wa ìfẹ́ gbigbona yin, ìbànújẹ́ yin, ati ìtara yin fun mi; bẹẹ ni mo sì tubọ yọ̀.

8. Nitori pe bi mo tilẹ fi ìwé mu inú yin bajẹ, emi ko kábámọ̀, (bi mo tilẹ ti kábámọ̀); nitori ti mo wòye pe ìwé naa mu yin banujẹ bi o tilẹ jẹ pe fun ìgbà diẹ. (2 Kor 2:2,4.)

9. Emi yọ̀ nisinsinyìí, ki i ṣe nitori ti a mu inú yin bàjẹ́, ṣugbọn nitori ti a mu inú yin bajẹ si ironupiwada: nitori ti a mu inú yin bajẹ bi ẹni ìwà-bi-Ọlọrun, ki ẹyin máṣe tipasẹ̀ wa pàdánù ni ohunkohun.

10. Nitori pe ibanujẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun a maa ṣiṣẹ ironupiwada si ìgbàlà ti kì i mu àbámọ̀ wá: ṣugbọn ibanujẹ ti ayé a maa ṣiṣẹ ikú. (A.A. 11:18.)

11. Kiyesi i, nitori ohun kannaa yìí ti a mu yin banujẹ fun bi ẹni iwa-bi-Ọlọrun, iru imura-sìṣẹ́ ti o mu jade ninu yin, wiwẹ ara yin mọ́ nkọ́ ibanujẹ nkọ́, ìpáyà nkọ́, ifojusọna nkọ́, ìtara nkọ́, ijẹni-niya nkọ́! Ninu ohun àmì kọọkan yìí ni ẹyin ti fi ara yin hàn bi alailẹbi ninu ọ̀ràn naa. (2 Kor 2:6; Rom 3:5.)

12. Nitori naa, bi mo tilẹ ti kọwe si yin, emi kò kọ ọ́ nitori ẹni ti o ṣe ohun buburu naa, tabi nitori ẹni ti a fi ohun buburu naa ṣe, ṣugbọn ki àníyàn yin nitori wa lè farahàn niwaju Ọlọrun. (ẹsẹ 8; 2 Kor 2:3,9; 1 Kor 5:1,2.)

13. Nitori naa a ti fi ìtùnú yin tù wa ninu; ati ninu ìtùnú wa, a yọ̀ gidigidi nitori ayọ Titu, nitori lati ọ̀dọ̀ gbogbo yin ni a ti tù ẹmi rẹ̀ lara. (ẹsẹ 6; 1 Kor 16:18.)

14. Bi mo tilẹ ti leri ohunkohun fun un nitori yin, a kò dojutì mi; ṣugbọn gẹgẹ bi awa ti sọ ohun gbogbo fun yin lotitọ, gẹgẹ bẹẹ ni ileri wa niwaju Titu si jasi otitọ. (ẹsẹ 4,6.)

15. Ọkan rẹ̀ si fà gidigidi si yin, bi oun ti nranti igbọran gbogbo yin, bi ẹ ti fi ibẹ̀rù ati iwárìrì tẹwọgbà á. (2 Kor 2:9; Filp 2:12.)

16. Mo yọ nitori pe ni ohun gbogbo mo ni igbẹkẹle ninu yin. (2 Tess 3:4.)

ORI 8.

**Apẹẹrẹ ti oore-ọfẹ ti Ọlọrun fun awọn ara Makedonia.**

PẸLÚPẸLÙ, ara, awa nsọ fun yin niti oore-ọfẹ Ọlọrun, ti a fifun awọn ìjọ Makedonia; (A.A. 16:9.)

2. Bi o ti jẹ pe ninu ọpọ ìdánwò ipọnju, ọpọlọpọ ayọ ati ìdégóngó àìní wọn ti kún àkúnwọ́sílẹ̀ ninu ọrọ ìlàwọ́ wọn. (2 Kor 9:11.)

3. Nitori mo jẹri pe gẹgẹ bi agbara wọn, ani ju agbara wọn, wọn ṣe e lati ifẹ inu ara wọn; (1 Kor 16:2.)

4. Wọn nfi ẹ̀bẹ̀ pupọ rọ̀ wa niti ẹbun atinuwa yìí, lati baa lè ni ipin ninu iṣẹ́-iranṣẹ fun awọn eniyàn mimọ. (A.A. 24:17; Rom 15:25,26,31; 2 Kor 9:1.)

5. Ati èyí, ki i ṣe bi awa ti rò rí, ṣugbọn wọn tètè kọ́ fi awọn tikarawọn fun Oluwa, ati fun wa, nipa ìfẹ́ Ọlọrun.

6. Tobẹẹ ti awa fi gba Titu niyanju pé, bi o ti bẹ̀rẹ̀ naa, bẹẹ ni ki o si pari ẹbun ọ̀fẹ́ yìí ninu yin pẹlu. (ẹsẹ 17; 2 Kor 12:18; ẹsẹ 16,10.)

7. Ṣugbọn bi ẹyin ti pọ lohun gbogbo, ni ìgbàgbọ́, ati ọ̀rọ̀, ati ìmọ̀, ati ninu aápọn gbogbo, ati ni ifẹ yin si wa, ẹ ri i wi pe ẹyin pọ si i ninu ẹ̀bùn ọfẹ yìí pẹlu. (2 Kor 9:8; 1 Kor 1:5; 12:13.)

**Apẹẹrẹ oore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi.**

8. Ki i ṣe nipa àṣẹ ni mo fi nsọ, ṣugbọn ki a le ri ìdí otitọ ìfẹ́ yin pẹlu, nipa aapọn ẹlomiran. (2 Kor 7:6.)

9. Nitori ẹyin mọ oore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi, pe bi oun ti jẹ ọlọ́rọ̀ ri ṣugbọn nitori yin o di talaka ki a lè sọ yin di ọlọ́rọ̀ nipa aini rẹ̀. (2 Kor 13:14; Filp 2:6,7.)

10. Ati ninu eyi ni mo fi imọran mi fun yin: nitori èyí ṣanfani fun yin, ẹyin ti o kọkọ bẹẹrẹ niwọn ọdun ti o kọja, ki i ṣe lati ṣe nikan, ṣugbọn lati fẹ́ pẹlu. (1 Kor 7:25; 2 Kor 9:2; 1 Kor 16:2,3.)

11. Njẹ nisinsinyìí, ẹ pari ṣiṣe naa pẹlu; ki o baa le ṣe pe, bi imura-tẹ́lẹ̀ fun ṣiṣe ti wà, bẹẹ ni ki ipari si wà lati inú agbara yin. (2 Kor 9:2.)

12. Nitori bi imura-tẹ́lẹ̀ bá wá ṣaaju, o jasi itẹwọgba gẹgẹ bi ohun ti eniyan bá ní, ki i ṣe gẹgẹ bi ohun ti kò ní. (Mk 12:43,44; Luk 21:3.)

13. Nitori emi kò fẹ ki awọn ẹlomiran wà ni ìrọ̀rùn, ki o si jẹ ipọnju fun yin,

14. Ṣugbọn pe nipa mimu-dọ́gba, pe ki ànìṣẹ́kù yin ni akoko yìí le ṣe deede aini wọn, ki àní-ṣẹ́kù tiwọn pẹlu baa lè ṣe deede aini yin: ki imudọgba baa le wà: (2 Kor 9:12.)

15. Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, "Ẹni ti o kó pọ̀ jù, kò ní nkan lé; ẹni ti o kó kere jù, kò ṣe aláìnító." (Eks 16:18.)

**Wíwá Titu ati awọn Arakunrin si Kọrinti.**

16. Ṣugbọn ọpẹ́ ni fún Ọlọrun ẹni ti o fi ìtara àníyàn kannaa yìí si ọkàn Titu fun yin.

17. Nitori kii ṣe pé oun gba ọ̀rọ̀ ìyànjú wá nikan ni; ṣugbọn bi oun ti ni itara púpọ̀, oun tikararẹ tọ̀ yin wa funrarẹ. (ẹsẹ 6.)

18. Awa ti rán arakunrin naa pẹlu rẹ̀, ìyìn ẹni ti o wa ninu ihinrere yíká gbogbo ìjọ; (2 Kor 12:18.)

19. Kii si ṣe bẹẹ nikan, ṣugbọn ẹni ti a ti yàn wá pẹlu lati ọ̀dọ̀ ijọ lati maa bá wa rìn kiri ninu ọ̀ràn oore-ọfẹ yìí, ti awa nṣe iranṣẹ rẹ̀ fun ogo Ọluwa ati imura-tẹ́lẹ̀ wa (1 Kor 16:3,4; ẹsẹ 4,6, 11.)

20. Awa nyẹra fun èyí, ki ẹnikẹni má baa ri wí sí wa ni ti ẹ̀bùn àtinúwá yìí ti awa pín.

21. Awa ngbèrò ohun rere, kii ṣe niwaju Oluwa nikan, ṣugbọn niwaju eniyan pẹlu. (Rom 12:17; 14:18.)

22. Awa si ti rán arakunrin wa pẹlu wọn, ẹni ti awa ri dájú nigba pupọ pé o ni itara ninu ohun pupọ, ṣugbọn ni isinsinyìí ni itara rẹ̀ tubọ pọ̀ si i nipa igbẹ́kẹ̀lé nla ti o ni si yin.

23. Bi ẹnikẹni ba nbeere ẹni ti Titu jẹ́, ẹlẹgbẹ́ ati olubaṣiṣẹ mi ni nitori yín: tabi niti awọn arakunrin wa ni ẹnikẹni nbèèrè, iranṣẹ ijọ ni wọn jẹ́, ati ogo Kristi. (Filp 2:25.)

24. Nitori naa ẹ fi ẹ̀rí ìfẹ́ yín hàn wọn niwaju ìjọ, ati iṣogo wa nitori yín. (2 Kor 7:14; 9:2.)

ORI 9.

**Ẹ̀bẹ̀ fún ipinfunni awọn eniyan mimọ.**

NISINSINYÌÍ, nipa ti ìpínfúnni fun awọn eniyan mímọ́, kò tun yẹ mọ́ fun mi lati kọwe si yin ju bẹẹ lọ. (2 Kor 8:4.)
2. Nitori mo mọ̀ imura-tẹ́lẹ̀ yin, èyí ti mo ti ṣogo fun awọn ara Makedonia nitori yín, pe, Akaia ti mura tán níwọ̀n ọdún kan ti o kọja itara yin sì ti ru ọ̀pọ̀lọpọ̀ soke. (2 Kor 7:4; Rom 15:26; A.A. 18:12; 2 Kor 8:10.)
3. Ṣugbọn mo ti rán awọn arakunrin, ki iṣogo wa nitori yin máṣe jásí asán niti ọ̀ràn yìí; pé gẹgẹ bi mọ ti wí, ki ẹyin lè mura tẹ́lẹ̀: (1 Kor 16:2.)
4. Ki o ma baa jẹ pé, bi awọn ninu ara Makedonia bá bá mi wá, ti wọn si ba yin ní aimura silẹ̀, ojú a si tì wa ki i ṣe ẹyin, niti igbẹkẹ̀lé yìí. (Gẹn 15:26.)
5. Nitori naa ni mo ṣe rò pe o yẹ lati gba awọn arakunrin niyanju, ki wọn ṣaaju tọ̀ yin wá, ki wọn si mura ẹ̀bùn yín sílẹ̀, ti ẹ ti se ileri tẹ́lẹ̀ ki a lè ṣe èyí naa silẹ, ki ó lè jásí bí ohun ẹ̀bùn, ki o má si ṣe dabi ti ifipágbà. (Gen 33:11; 1 Sam 25:27; 2 Kor 12:17,18; Filp 4:17.)

**Ọlọrun fẹ́ onínúdídùn ọlọ́rẹ.**

6. Ṣugbọn èyí ni mo wi pé: Ẹni ti o ba funrugbin kiun, kiun ni yoo ká; ẹni ti o ba si funrugbin pupọ, pupọ ni yoo ká. (Gal 6:7,9.)
7. Ki olukuluku eniyan ṣe gẹ́gẹ́ bi o ti pinnu lọkan rẹ̀; kii ṣe afilọ́ra ṣe, tabi ti àìgbọdọ̀ má ṣe; nitori Ọlọrun fẹ́ oninudidun ọlọ́rẹ. (Deut 15:7,10; Eks 25:2; Rom 12:8; 2 Kor 8:12.)
8. Ọlọrun si lè mu kí gbogbo oore-ọ̀fẹ́ maa bisi i fun yin; ki ẹyin ti o ni anitó ohun gbogbo nigbagbogbo, lè maa pọ̀ si i ni iṣẹ rere gbogbo: (Ef 3:20; Filp 4:19.)
9. Gẹ́gẹ́ bi a ti kọ ọ pé, "O ti fọ́nká; o ti fifun awọn tálákà: ododo rẹ̀ duro laelae." (Psm 112:9.)
10. Njẹ ẹni ti nfi irúgbìn fun afunrugbin, ati àkàrà fún ounjẹ, yoo fi irúgbìn fún yin, yoo si sọ ọ di púpọ̀ fún irúgbìn, yoo si mu èso ododo yin bi si i. (Isa 55:10; Hos 10:12.)
11. Bẹẹ ni a o sọ yin di ọlọ́rọ̀ nínú ohun gbogbo, fun ìlàwọ́ yin gbogbo ti nṣiṣẹ ọpẹ́ si Ọlọrun nipa wa. (1 Kor 1:5,11.)
12. Nitori iṣẹ-iranṣẹ ìsìn yìí kò kun ìwọ̀n aini awọn eniyan-mimọ nikan, ṣugbọn o tubọ pọ̀ si i nipa ọpọlọpọ ọpẹ́ sí Ọlọrun. (2 Kor 8:14.)
13. Nitori ìdúró (yin) lábẹ́ ìdánwò iṣẹ́-ìsìn yìí, wọn yoo yin Ọlọrun lógo fun ìgbọ́ràn yin ni gbígba ihinrere Kristi, ati nipa ìlàwọ́ ìdáwó yin fun wọn ati fun gbogbo eniyan; (2 Kor 8:4; Rom 15:31; Matt 9:8; 2 Kor 2:12.)
14. Nigba ti awọn tikarawọn pẹlu ẹ̀bẹ̀ fun yin nṣàfẹ́rí yin nitori ọ̀pọ̀ oore-ọfẹ Ọlọrun ti nbẹ inu yin.
15. Ọpẹ́ ni fun Ọlọrun nitori aláìlèfẹnusọ ẹ̀bùn rẹ̀! (2 Kor 2:14; Rom 5:15,16.)

ORI 10.

**Ẹ̀sì Paulu sí ẹ̀sùn àìlera ati ojo.**

SUGBỌN emi Paulu tikarami fi inú tútù ati ìwà pẹlẹ Kristi bẹ̀ yín, emi ẹni irẹ̀lẹ̀ loju yin nigba ti mo wà laarin yin, ṣugbọn nigba ti emi kò sí, mo di ẹni ìgboyà si yin. (Gal 5:2; Rom 12:1.)
2. Ṣugbọn emi bẹ̀ yin pe nigba ti mo wà laarin yin, ki emi baa lè lo ìgboyà pẹlu igbẹkẹle naa eleyìí ti mo ti fọkan si lati fi dojukọ awọn kan, ti nfura si wa bi ẹni ti nrin nipa ti ara. (1 Kor 4:21; 2 Kor 13:2,10.)
3. Nitori pe bi awa tilẹ̀ rin nipa ti ara, ṣugbọn awa ko jagun nípa ti ara: (ẹsẹ 2.)
4. Nitori ohun ìjà wa kii ṣe ti ara, ṣugbọn o lagbara ninu Ọlọrun lati wó ibi gíga palẹ̀; (1 Tim 1:18; 2 Tim 2:3; A.A. 7:22; Ef 6:12.)
5. Awa nsọ gbogbo èrò kalẹ̀, ati gbogbo ohun giga ti ngbe ara rẹ̀ ga si

ìmọ̀ Ọlọrun, awa si ndi gbogbo èrò ni igbekun wá si ìtẹríba fun Kristi; (1 Kor 1:19; Isa 2:11,12; 2 Kor 9:13.)

6. Awa si ti mura tán lati jẹ gbogbo aigbọran níyà, nigba ti igbọran yin bá pe. (2 Kor 2:9.)

7. Ẹyin si nwo nkan gẹ́gẹ́ bi wọn ti fi hàn lode. Bi ẹnikẹni bá gbẹkẹle ara rẹ̀ pe, ti Kristi ni oun, jẹ kí o rán ara rẹ̀ létí ninu ara rẹ̀ pé, bi oun ti jẹ ti Kristi, gẹgẹ bẹẹ ni awa pẹlu si jẹ ti Kristi. (Jhn 7:24; 1 Kor 1:12; 14:37.)

8. Nitori bí mo tilẹ̀ nṣogo àserékọjá nitori àṣẹ wa, ti Oluwa ti fifun wa fun ìdàgbàsókè yín kii ṣe fun ìbìṣubu yín, ojú ki yoo ti mi: (2 Kor 7:4; 13:10.)

9. Ki o máṣe dabi ẹni pé emi nfi ìwé-kíkọ dẹruba yin.

10. Nitori wọn wi pe, "Iwe rẹ wuwo, wọn si lagbara; ṣugbọn irisi rẹ̀ jẹ alailera, ọ̀rọ̀ rẹ kò nilari." (1 Kor 2:3; Gal 4:13,14; 1 Kor 1:17.)

11. Ki irú eniyan bẹẹ ro bayìí pe, irú ẹni ti awa jẹ ninu ọ̀rọ̀ nipa ìwé-kikọ nigba ti awa kò sí, irú bẹẹ ni awa si jẹ́ ninu iṣe pẹlu nigba ti awa bá wà.

12. Nitori pe awa kò dáṣà lati ka ara wa mọ́, tabi lati fi ara wa wé awọn miran ninu wọn ti nyin ara wọn; ṣugbọn awọn tikarawọn jẹ aláìlóye bi wọn ti nfi ara wọn díwọ̀n ara wọn, ti wọn sì nfi ara wọn wé ara wọn. (2 Kor 3:1; 5:12.)

**Paulu duro lai rekọja iṣẹ ti Ọlọrun yan.**

13. Ṣugbọn awa kò ṣogo rekọja ààlà wa, ṣugbọn nipa ààlà ìwọ̀n ti Ọlọrun ti pin fun wa, èyí tí o mu un ki o ṣeeṣe lati de ọ̀dọ̀ yin. (ẹsẹ 15.)

14. Nitori àwa kò nawọ́ wa rekọja rárá, bi ẹni pé awa kò de ọ̀dọ̀ yin: nitori awa tilẹ̀ dé ọ̀dọ̀ yin pẹlu ninu ihinrere Kristi. (2 Kor 2:12.)

15. Awa kò ṣogo rékọjá ààlà wa, eyi ni; lori iṣẹ ẹlomiran; ṣugbọn awa ni ìrètí pe, bi igbagbọ yin ti ndagba si i, gẹgẹ bi ààlà wa àwa o di gbígbéga lọdọ yin si i lọpọlọpọ. (Rom 15:20; 2 Tess 1:3.)

16. Ki a baa lè waasu ihinrere ni awọn ilu ti nbẹ niwaju yin, ki a má sì ṣogo ninu ààlà ẹlomiran nipa ohun ti o wa ni arọwọtó.

17. "Ṣugbọn jẹ ki ẹni ti o ba nṣogo, ki o maa ṣogo ninu Oluwa." (Jer 9:24; 1 Kor 1:31.)

18. Nitori ki i ṣe ẹni ti nyin ara rẹ̀ ni o ni itẹwọgba, bikoṣe ẹni ti Oluwa bá yin. (Rom 2:29; 1 Kor 4:5.)

## ORI 11.

**Paulu kìlọ̀ nipa awọn ẹlẹ́kọ èké.**

EYIN iba gbà mi diẹ, ninu wèrè (òmùgọ̀) mi: ati nitootọ, ẹ gbà mi. (ẹsẹ 16,17,21; 2 Kor 5:13.)

2. Nitori pe emi njowú lori yin ni ti owú ẹni iwa-bi-Ọlọrun: nitori ti mo ti fi yín fún ọkọ kan, ki emi baa lè mu yin wá bi wundia ti o mọ sọdọ Kristi. (Hos 2:19; Ef 5:26,27; 2 Kor 4:14.)

3. Ṣugbọn ẹ̀rù nbà mi, ki o má baa jẹ pe, bi ejò ti tan Efa jẹ nipasẹ arékérekè rẹ̀, èrò-ọkàn yin yoo bàjẹ́ kuro ninu otitọ-inu ati ìwà mímọ́ yin sí Kristi. (Gen 3:4; Jhn 8:44.)

4. Nitori bi ẹnikan wá ti o si waasu Jesu miran, yàtọ̀ si èyí ti a ti waasu ri, tabi bi ẹyin ba gba ẹmi miran, yatọ si èyí ti ẹ ti gbà, tabi ihinrere miran, yatọ sí èyí ti ẹ ti gbà, ti ẹ si ti yára tẹwọ gba a. (1 Kor 3:11; Rom 8:15; Gal 1:6–8.)

5. Nitori mo rò pe emi kò rẹ̀hìn ni ohunkohun si awọn Aposteli gígagíga naa. (2 Kor 12:11; Gal 2:6.)

6. Ṣugbọn bi mo tilẹ jẹ òpè ninu ọ̀rọ̀ sisọ, kii ṣe ninu ìmọ̀; ṣugbọn ni ọ̀nàkọnà awa ti fi èyí hàn dajudaju fun yin ninu ohun gbogbo. (1 Kor 1:17; Ef 3:4; 2 Kor 4:2.)

**Paulu tikararẹ̀ ti ara rẹ̀ lẹ́hìn.**

7. Tabi ẹ̀ṣẹ̀ ni mo dá bi emi ti nrẹ ara mi sílẹ̀ ki a lè gbé yín ga, nitori ti mo waasu ihinrere Ọlọrun fun yin lọfẹ? (2 Kor 12:13; 1 Kor 9:18.)

8. Emi nja ìjọ miran ni olè, nipa gbigba ìpèsè-owó ki emi baa lè sìn yín. (Filp 4:15,18.)

9. Nigba ti mo sì wà pẹlu yin, ti mo

si ṣe alaini, emi kò dẹrùpa ẹnikẹni: nitori ohun ti mo ṣe alaini ni awọn ará ti o ti Makedonia wá ti mú wá. Bẹẹ ni nínú ohun gbogbo mo pa ara mi mọ́ lati máṣe jẹ ẹrù fun yin, emi yoo si maa pa ara mi mọ́ bẹẹ. (2 Kor 12:13,14.)

10. Ó jẹ́ otitọ Kristi ti nbẹ nínú mi pe kò si ẹni ti o lè da mi lẹkun iṣogo yìí ni gbogbo ẹkùn Akaia. (Rom 9:1; 1 Kor 9:15; A.A. 18:12.)

11. Nitori kinni? Nitori emi kò fẹ́ràn yin ni bi? Ọlọrun mọ̀. (2 Kor 12:15.)

12. Ṣugbọn ohun ti mo nṣe ni emi o si maa ṣe, ki emi lè mu ẹ̀fẹ̀ kuro lọwọ awọn ti wọn nfẹ́ ṣẹ̀fẹ̀, pé ninu ohun ti wọn nṣogo, ki a le ri wọn gẹgẹ bi àwa. (1 Kor 9:12.)

13. Nitori irú awọn eniyan bẹẹ ni awọn èké Aposteli, awọn ẹni ti nṣiṣẹ ẹ̀tàn, ti npa ara wọn dà di Aposteli Kristi. (Gal 1:7; 2 Pet 2:1; Filp 3:2.)

14. Kìí si i ṣe ohun iyanu; nitori Satani tikararẹ̀ npa ara rẹ̀ dà di angẹli imọ́lẹ̀.

15. Nitori naa ki i ṣe ohun nla bi awọn iranṣẹ rẹ̀ pẹlu bá pa ara wọn dà bi awọn iranṣẹ òdodo; igbẹhin awọn ẹni ti yoo ri gẹgẹ bi iṣẹ́ wọn. (Filp 3:19.)

**Ó jẹ́ ọranyàn fun Paulu lati maa ṣògo.**

16. Mo si tun wi pe, ki ẹnikẹni máṣe rò pe aṣiwèrè (òmùgọ̀) ni mí; ṣugbọn bi bẹẹ ba ni, ẹ gbà mi bi aṣiwèrè (òmùgọ̀) ki emi lè gbé ara mi ga diẹ. (ẹsẹ 1.)

17. (Ohun ti emi nsọ, emi ko sọ ọ nipa ti Oluwa, ṣugbọn bí aṣiwèrè (òmùgọ̀) ninu igbẹkẹle iṣogo yìí. (1 Kor 7:6,12,25; A.A. 9:24,25.)

18. Ọpọlọpọ ni o nṣògo nipa ti ara, emi o ṣògo pẹlu.) (Filp 3:3,4.)

19. Nitori ẹyin fi inú dídùn gba awọn aṣiwèrè (òmùgọ̀), nigba ti ẹyin tikarayin jẹ́ ọlọgbọ́n.

20. Nitori ẹyin farada a bi ẹnikan ba sọ yin di òndè, bi ẹnikan bá jẹ yin run, bi ẹnikan ba gbà lọwọ yin, bi ẹnikan bá gbé ara rẹ̀ ga, bi ẹnikan ba gbá yin loju.

21. Emi nwi lọna ẹ̀gàn, bi ẹni pe awa jẹ alailera. Ṣugbọn ninu ohunkohun ti ẹnikan ti ni ìgboyà (emi nsọ̀rọ̀ bi òmùgọ̀) emi ní ìgbóyà pẹlu. (2 Kor 10:10; Filp 3:4.)

**Ìdí tí Paulu fi lè ṣogo.**

22. Heberu ni wọn bí? Bẹẹ ni emi. Israẹli ni wọn bi? Bẹẹ ni emi. Irú ọmọ Abrahamu ni wọn bi? Bẹẹ ni emi. (A.A. 6:1; Filp 3:5; Rom 9:4.)

23. Iranṣẹ Kristi ni wọn bi? (Emi nsọ bi òmùgọ̀) mo ta wọ́n yọ; ni ti làalàa lọpọlọpọ, niti pàṣán mo rékọjá, niti túbú nigbakugba, niti fifẹrẹ kú nigbapúpọ̀. (1 Kor 15:10; A.A. 16:23; 2 Kor 6:5.)

24. Nigba marun ni mo gba paṣan ogóji din kan lọwọ awọn Ju. (Deut 25:3.)

25. Nigba mẹta ni a fi ọ̀gọ̀ lù mí, ẹkanṣoṣo ni a sọ mi ni okuta, ẹẹmẹta ni ọ̀kọ̀-ojuomi rì mí, ọsan kan ati ọ̀ru kan ni mo wà ninu ibú. (A.A. 16:22; 14:19.)

26. Ni ìrìn àjò nigbakigba, ninu ewu omi, ninu ewu awọn ọlọ̀ṣà, ninu ewu awọn ará ilu mi, ninu ewu awọn Keferi, ninu ewu ni ilú, ninu ewu ni aginjù, ninu ewu lójú òkun, ninu ewu laarin awọn èké arakunrin. (A.A. 9:23; 14:5; 21:31; Gal 2:4.)

27. Ninu lãálàá ati irora, ninu ìṣóòru nigbàkugbà, nínú ebi ati orungbẹ, ninu ààwẹ̀ nigbakugba, ninu òtútù ati ìhòhò. (1 Tess 2:9; 1 Kor 4:11; 2 Kor 6:5.)

28. Pẹlu nkan wọnyìí ti o jẹ ti òde, ọ̀pọ̀ ni èyí ti nwọ́jọ tì mi lójoojúmọ́, àní aníyàn fun gbogbo ìjọ.

29. Tani o ṣe alailera, ti emi ko ṣe alailera? Tabi a mú kọsẹ̀, ti ara mi kò gbiná? (1 Kor 9:22.)

30. Bi emi yoo bá ṣogo, emi o kúkú maa ṣogo nipa awọn nkan ti o jẹ́ ti ailera mi. (1 Kor 2:3.)

31. Ọlọrun ati Baba Oluwa wa Jesu Kristi, ẹni ti o jẹ́ olùbùkún jùlọ laelae mọ̀ pe emi kò ṣèké. (Gal 1:20; Rom 9:5.)

32. Ni Damasku, baalẹ̀, ti o wà labẹ ọba Areta fi ẹgbẹ́ ogun ká ìlú awọn ara Damasku mọ́, o nfẹ mi lati mú: (A.A. 9:24,25.)

33. Ati lójú fèrèsé ninu agbọ̀n ni a si ti sọ̀ mi kalẹ lẹhin odi, ti mo si bọ́ lọ́wọ́ rẹ̀.

ORI 12.

BI kò ti sí ohun ti a le ri gba nibẹ, sibẹ, emi yoo ṣògo, emi o wa si ìran ati iṣipaya Oluwa. (Kol 11:30; ẹsẹ 7; Gal 1:12; 2:2.)

2. Emi mọ ọkunrin kan ninu Kristi ni ọdun mẹrinla sẹhin, yálà ninu ara ni, emi kò mọ̀; tabi kuro ninu ara, emi kò mọ̀; Ọlọrun ni o mọ̀: a gbé irú eniyan bẹẹ lọ sí ọ̀run kẹta. (Rom 16:7; Ef 4:10; 2 Kor 11:11.)

3. Bẹẹ ni Emi mọ irú ọkunrin bẹẹ (yálà ní ara ni, tabi kúrò ninu ara ni, emi ko mọ: Ọlọrun mọ̀);

4. Pe a gbé e lọ sókè si Paradise, ti o si gbọ́ ọ̀rọ̀ ti a kò sì lè sọ, ti ko tọ́ fun eniyan lati máa sọ. (Luk 23:43; Ifh 6:9–11.)

5. Nipa irú ẹni bẹẹ ni emi o maa ṣògo: ṣugbọn nipa ti emi tikarami emi ki yoo ṣògo, bikoṣe ninu ailera mi.

6. Nitori pe bi emi tilẹ nfẹ maa ṣògo, emi ki yoo jẹ aṣiwèrè (òmùgọ̀); nitori pe emi o sọ otitọ: ṣugbọn mo kọ̀, ki ẹnikẹni ma baa fi mi pè ju ohun ti o ri tí emi jẹ lọ, tabi ju èyí ti o gbọ́ lẹnu mi. (2 Kor 10:8; 11:16.)

7. Ati nitori ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìṣípayá, ki emi ma baa gbé ara mi ga rekọja, a si ti fi-ẹ̀gun kàn si mi lara, iranṣẹ Satani lati pọ́n mi loju, ki emi má baa gberaga rekọja.

8. Nitori nkan yìí ni mo ṣe bẹ Oluwa nigba mẹta pe, ki o lée kúrò lara mi. (Matt 26:44.)

9. Oun si wi fun mi pé, "Oore-ọfẹ mi tó fun ọ: nitori pe a sọ agbara mi di pípé ninu ailera." Nitori naa tayọ̀tayọ̀ ni emi o kuku maa fi ṣogo ninu ailera mi, ki agbara Kristi lè maa gbé inú mi. (Filp 4:13; 2 Kor 11:30; 1 Pet 4:14.)

10. Nitori naa emi ní inú didùn ninu ailera gbogbo, ninu ẹ̀gàn gbogbo, ninu aini gbogbo, ninu inúnibíni gbogbo, ninu wahala gbogbo nitori Kristi: nitori nigba ti mo bá jẹ́ alailera, nigba naa ni mo di alagbara. (2 Kor 2:3; Tit 1:13; 2 Kor 10:8.)

**Iṣẹ-àmì aposteli tootọ́.**

11. Mo di omugọ nipa ṣiṣogo; ẹyin ni o fi ipá mu mi ṣe e: nitori ti o tọ́ ti ẹ ba yìn mi: nitori ti emi kò rẹ̀hìn lohunkohun si awọn Aposteli gígagíga naa, bi emi kò tilẹ jámọ́ nkankan.

12. Nitootọ a ti ṣe iṣẹ́-àmì Aposteli laarin yin ninu suuru gbogbo, ninu iṣẹ-àmì, ati iṣẹ-iyanu, ati iṣẹ́-agbára. (Rom 15:18,19.)

13. Nitori ninu kinni ohun ti ẹyin ṣe rẹ̀hìn si ijọ miran, bikoṣe niti pe emi tikarami ko jẹ oniyọnu fun yin? Ẹ dari aṣiṣe yìí jì mí. (1 Kor 9:12,18; 2 Kor 11:7.)

14. Kiyesi i, ìgbà kẹta yìí ni mo mura tán lati tọ̀ yin wá; emi ki yoo si jẹ oniyọnu fun yin: nitori ti emi kò wá nkan yín, bikoṣe ẹyin tikarayin: nitori tí kò tọ́ fun awọn ọmọ lati maa to ìṣura jọ fún awọn òbí wọn, bikoṣe awọn obi fun awọn ọmọ wọn. (2 Kor 13:1; 1 Kor 10:24,33; 4:14,15; Owe 19:14.)

15. Emi o si fi ayọ ná owo, emi o si ná ara mi fún ọkàn yin nitootọ; bi mo tilẹ fẹ yin lọpọlọpọ, diẹ ni a haa fẹran mi? (Filp 2:17; 1 Tess 2:8.)

16. Ṣugbọn o dara bẹẹ ti emi kò dẹruba yín: ṣugbọn bi ọlọgbọ́n, arékérekè, emi nfi ẹ̀tàn mu yin.

17. Emi ha rẹ́ yin jẹ nipa ẹnikẹni ninu awọn ti mo rán si yin bi?

18. Mo bẹ Titu, mo sì rán arakunrin kan pẹlu rẹ̀; Titu ha rẹ́ yin jẹ bi? Nipa ẹ̀mí kannaa kọ àwá rìn bi? Ọ̀nà kannaa kọ àwá tọ̀ bi? (2 Kor 8:6,16,18.)

**Ìpè sí ironupìwàdà.**

19. Ẹyin ha rò pe ni gbogbo akókò yìí awa kàn nṣe àwáwí fun yin ni? Ni iwaju Ọlọrun ni awa n sọrọ ninu Kristi: ṣugbọn awa nṣe ohun gbogbo,

olufẹ ọwọ́n, lati gbe yin ro ni. (Rom 9:1; 2 Kor 10:8.)

20. Nitori ẹ̀rù nbà mi pe, nigba ti mo bá dé, emi ki yoo bá yin gẹgẹ bi irú ẹ̀yí tí mo fẹ́, ati pe ẹyin o sì rí mi gẹgẹ bi irú ẹ̀yí tí ẹyin kò fẹ́: Ki ìjà, owú-jíjẹ, ìbínú, ìpinyà, ìsọ̀rọ̀-ẹni-lẹhin, ìjírọ̀sọ, ìfẹgẹ̀, ìrukèrudò, ma baa wà: (2 Kor 2:1–4; 1 Kor 1:11; 3:3.)

21. Ati nigba ti mo ba sì padà dé, ki Ọlọrun mi má baa rẹ̀ mi sílẹ̀ loju yín, ati ki emi ma baa sọkún nitori ọpọlọpọ awọn ti o ti ṣẹ̀ naa ti kò sì ronupìwàdà ẹ̀ṣẹ̀ iwa-eeri, ati ti àgbèrè, ati ti wọ̀bìa ti wọn ti dá. (2 Kor 2:1,4; 13:2; Gal 5:19.)

ORI 13.

EYÍ ni o di ìgbà kẹta ti emi ntọ yin wá. Ni ẹnu ẹlẹri meji tabi mẹta ni a o fi ìdí ọ̀rọ̀ gbogbo múlẹ̀. (2 Kor 12:14; Deut 19:15; Matt 18:16.)

2. Mo ti sọ fun yin ṣaaju, mo si nsọ fun yin tẹ́lẹ̀, bi ẹni pe mo wà pẹlu yin nigba keji, ati bi emi kò ti sí lọdọ yin ni isinsinyìí, mo kọwe si awọn ti o ti ṣẹ̀ naa, ati si gbogbo awọn ẹlomiran, pe bi mo ba tun padà wá, emi ki yoo da wọn si:

3. Niwọn bi ẹyin ti nwá àmì Kristi ti nsọ̀rọ̀ ninu mi, ẹni ti kii ṣe ailera si yin, ṣugbọn ti o jẹ agbara ninu yín. (Matt 10:20; 1 Kor 5:4; 2 Kor 9:8; 10:4.)

4. Nitori pe a kàn an mọ́ agbelebu nipa ailera, ṣugbọn oun wa láàyè nipa agbara Ọlọrun. Nitori awa pẹ̀lu jásí alailera ninu rẹ̀, ṣugbọn awa o wà láàyè pẹlu rẹ̀ nipa agbara Ọlọrun si yin. (Filp 2:7,8; 1 Pet 3:18; Rom 6:4,8; ẹsẹ 9.)

5. Ẹ maa wádìí ara yín, bi ẹyin bá wà ninu igbagbọ; ẹ maa dán ara yin wo. Tabi ẹyin tikarayin kò mọ̀ ara yin pe Jesù Kristi wa nínú yin? Afi bi ẹyin bá jẹ́ awọn ti a tanù. (Jhn 6:6; 1 Kor 11:28; 9:27.)

6. Ṣugbọn mo ni igbẹkẹle pe ẹyin o mọ̀ pe, awa kii ṣe awọn ti a tanù.

7. Njẹ awa ngbadura si Ọlọrun, ki ẹyin máṣe ṣe ibi-kibi kan; kii ṣe nitori ki awa lè farahan bi awọn ti o ti tayọ, ṣugbọn ki ẹyin le maa ṣe ẹ̀yí ti o dara bi awa tilẹ̀ dabi awọn ti a tanù.

8. Nitori awa kò lè ṣe ohun kan lòdì si otitọ, bikoṣe fun otitọ.

9. Nitori awa nyọ̀, nigba ti awa jẹ alailera, ti ẹyin si jẹ alágbara; ẹ̀yí ni awa si ngbadura fun pẹlu, ani pípé yin. (2 Kor 11:30; 12:10.)

10. Nitori idi ẹ̀yí, nigba ti emi kò sí, mo kọwe nkan wọnyìí pe, nigba ti mo bá de, ki emi má baa lo ikanra, gẹ́gẹ́ bi aṣẹ ti Oluwa ti fifun mi, lati mu dàgbà-sókè, kii ṣe lati fi párun. (2 Kor 2:3; Tit 1:13; 2 Kor 10:8.)

**Itọni ati ìkíni.**

11. Ni akotan, ará, ódìgbóṣe, Ẹ ṣe atunṣe ọ̀nà yin, ẹ túјúká, ẹ jẹ oninu kan, ẹ maa wà ni alaafia, Ọlọrun ìfẹ́ ati ti alaafia yoo wà pẹlu yin. (Rom 15:33; Ef 6:23.)

12. Ẹ fi ifẹnukonu mímọ́ ki ara yin.

13. Gbogbo awọn eniyan mímọ́ ki yin. (Filp 4:22.)

**Oore-ọfẹ.**

14. Oore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa, ati ifẹ Ọlọrun, ati *idapọ ti Ẹmi Mimọ, ki o wà pẹlu gbogbo yin. Amin.

---

(14) *"Idapọ ti Ẹmi-Mímọ́" Tabi "Àjọpín ninu Ẹmi Mímọ́."